# ELETI ỌFẸ

A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ...

VOL. XIV No 527 LAGOS SATURDAY JULY 7, — JULY 13, 1962 KOBO MEJI (2D)


# Egbe Afeni Fere (AG)

## Nfo Baba Egbe Wa Ni Igbekun Awon Omo Egbe Tuka

IBADAN—Gudugbẹ fọ ni ilu yi ni ana ọjọ Jimọ nigbati irohin tan kakiri wipe Oloye Samuel Ladoke Akintọla, ti o wa ni ihamọ ni Olokemeji

pe awọn ogunna gLongbo mẹta ninu ọmọ ẹgbẹ Afẹni-

fẹre (AG) lejọ si Kotu-ganran pe ki nwọn ye lo orukọ ẹgbẹ na mọ. Awọn ti Oloye Akintọla pe ni ẹjọ ni Oloye Ọbafemi Awolọwọ, Anthony Enahoro ati Alhaji S. O. Gbadamọsi.

Ninu iwe ipẹjọ na, Oloye Akintọla ni on fẹ ki adajọ fi ofin le e, ki awọn ti on pe lejọ yi ati awọn ọmọlehin wọn ye lo orukọ Action Group ti a ndape ni ẹgbẹ Afẹni-fẹre mọ, o ni lẹhinna on fẹ ki nwọn wa ṣe iṣiro gbogbo owo ẹgbẹ bi nwọn ti na an ti lati ọdun kẹwa ti awọn ti bẹrẹsi ṣe ẹgbẹ na.

Orukọ awọn meji ti nwọn tun pẹlu Oloye Akintọla pe ẹjọ yi ni Ayọ Roshiji ati Omitowoju.


## STAR LAGER

OFF-LICENCE SELLING PRICES

| | | |
|---|---|---|
| STAR | large size bottle ... | 2/9 |
| STAR | small size bottle ... | 1/7 |

Selling price at Bars, Hotels and other on-licence premises

| | | |
|---|---|---|
| STAR | large size bottle ... | 3/- |
| STAR | small size bottle ... | 1/9 |



Advt. NO. 109

## IKEDE

OWO ATIJỌ TI WEST AFRICAN CURRENCY BOARD

Lati ọjọ kini oṣu July, 1962, eyiti iṣe oṣu keje ọdun yi, gbogbo owo atijọ patapata ni pepa kọrẹnsi ati ṣile pẹlu owo wẹwẹ miran bẹ ti West African Currency Board ti kuro labẹ ofin ni jake jado ilẹ Nigeria. Owo yi ko ni ṣe na mọ fun sisan gbese tabi ki o wulo fun tita tabi rira ọja ni ṣọpu ati ni ọja. Ṣugbọn owo wọnyi ṣi ni iye lori ati wipe ẹnyin si le ṣe paṣi-parọ wọn ni gbogbo Bank.

Lati ran yin lọwọ, Central Bank ti Nigeria ti ṣe eto pẹlu gbogbo Bank pe ki wọn ma ṣe dẹkun lati ma ṣe paṣi-parọ owo pepa kọrẹnsi ti atijọ l'ọfẹ fun awọn enia titi di ipari oṣu September, 1962, ti nṣe oṣu kẹsan ọdun yi ati fun owo ṣile ati awọn isọngbe rẹ titi di ipari oṣu December, ti nṣe ipari ọdun yi.

Nitorina a bẹ gbogbo yin patapata lati mu owo atijọ ti o mbẹ lọwọ yin lọ si Bank ti o ba sun mọ yin ki E lọ ṣe paṣi-parọ wọn l'ọfẹ si owo Nigeria titun ti Central Bank fi si ode ni iwọn ọdun mẹta sẹhin. Ẹ ma ṣe jafara.

Gbogbo eniti ko ba parọ owo atijọ ọwọ rẹ si owo Nigeria titun titi asiko ti a fi silẹ fun yin ba fi pari yio san owo fun Bank nigbati o ba fẹ ṣe paṣi-parọ owo atijọ rẹ lẹhin ọjọ wọn yi.

CENTRAL BANK OF NIGERIA,
LAGOS.

W. A. TIBBLES
GENERAL MANAGER

# Awo Irawo

## Eyi ni awon nkan ti yio sele si o ninu ose ti mbo.

AQUARIUS (Jan 22–Feb 20) Maṣe bẹru lati tun dawọ le awọn nkankan ti o ti ṣe ni alaipari, wa yọn ṣe si rere.

PISCES (Feb 21–Mar 20) Orẹ ifẹ kan ti o ti nfẹ ba oni tirẹ kan sọ, bi o ṣe lọṣẹ yi, yio si dara.

ARIES (Mar 21–April 20) O ngbimoran lati lọ si idalẹ nipa owoṣiṣe tabi fun iṣe kan; lọ, ibẹ yio ṣe ọ ni anfani.

TAURUS (April 21–May 20) Kiloṣe ti o ko fi fẹ fi itẹ ti o ni si Olufẹ rẹ kan? Jade otitọ fun un.

GEMINI (May 21–June 21) Awọn enia kan a fẹ gbe ọ gun ayan pẹlu awọn ewotan kan ti yio fi han o la'i fi pọn ọ lẹ. Ko apọn'e ni jijo.

CANCER (Jun 22–July 23) Laipẹ yi wa rin irin-ajo kan, ki o maṣe pe nibẹ nitori ọrọ larin ẹbi kan a jẹki o tete pada bọ.

LEO (July 24–Aug 22) Wa ri asiki kekere kan lọnd iṣẹ rẹ laipẹ yi, ki o dimu sinsin, ki o maṣe jẹki o bọ.

VIRGO (Aug 23–Sept 23) Maṣe ṣe iye meji lati ṣe iṣẹ ojiji kan ti nwọn yio pe ọ si lọṣẹ yi. Ire ni.

LIBRA (Sep 24–Oct 23) Kilo mba e lọkan jẹ? Ju gbogbo re silẹ adun ni gbẹhin ewuro. Awọn kan yio gba imọran lọwọ re lojọ Monday.

SCORPIO (Oct 24–Nov 22) Awọn kan a fẹ mu ọ binu larin ọsẹ yi, maṣe binu rara. Wa si pade asiki kan.

SAGITTARIUS (Nov 23–Dec 22) Ha iwa ọmọluwabi nibi iṣẹ rẹ, ki o si ṣe iṣẹ rẹ na tọkan-tọkan, gbogbo alamọri rẹ a jasi daradara.

CAPRICORN (Dec 23–Jan 12) Iṣẹ pọ nipọ ti wa ṣe, maṣe ṣe ọlẹ rara. Ki o si ṣọra la'i towọ bọ ọrọ aṣiri pẹlu enia.

# Ololą Head Se Abewo U.A.C.

Laipe yi ni Ọlọla Viscount Head, K.C.M.G., C.B.E., M.C., Olori aṣoju ijọba ilẹ Gẹsi ni Nigeria, ṣe ibẹwo ọpọlọpọ awọn ibi iṣẹ aje ati ti ẹkọ kikọ ti ẹgbẹ onisowo U. A. C., dasilẹ. Ọgbẹni D. G. Stewart-Smith, ti iṣe ajiroro iṣẹ aje ati olori aṣoju iṣẹ owo ni ilẹ Nigeria fun ilẹ Gẹsi, tẹle e lẹhin kakiri. Ọgbẹni J. B. Davies, O.B.E., ti nṣe alaga ẹgbẹ onisọwo U.A.C., ti ilẹ Nigeria ni o fi ibi iṣẹ nwọnyi han an.

Ibẹwo na fun ọlọla Head ni anfani lati foju ri ọpọlọpọ ibi iṣẹ aje ti awọn ẹgbẹ na ni ipin si, ifihan awọn nkan miran ti ẹgbẹ na ni fun ṣiṣẹ ni ọjọ iwaju, ati lati le ni itẹlọrun fun awọn iṣẹ iyebiye fun ilọsiwaju ti awọn ẹgbẹ onisowo na si nṣe fun ẹkọ iṣẹ owo, ati alakoso iṣẹ fun ọmọ Nigeria.

Ọlọla Head si pari ibẹwo rẹ na si ibi ti a nkọ awọn oṣiṣẹ ẹgbẹ onisowo yi ni ẹkọ ni Igbobi lọjọ na.

---

**Gegebi Itan Ogbeni J. Ola. Wins, Lori "Eru Aiye Ma Mba Mi." Eo tun Ma Ri Pambabari Re Ka Lose Ti O Mbo.**

---

CARSON PAINTS AND VANISHES



SOLE AGENT:
IKORODU TRADING COMPANY,
20 & 28, Balogun Street, Lagos.

E MA SE FI OMI SOFO MO




E Kilo Fun Awon Omo Nyin

# Omo araiye ko feni fe're

(Lati owo Abiola Bolarinwa)

Agbado ijọsi ti wọn di mọ ẹru Adẹtẹ abami ẹda yi, wọn ko mọ pe ire ati ọla ni wọn fi da lọla. Adẹtẹ yi fi ada rẹ pale o si gbin awọn agbado yi si inu ilẹ ti o ti pa na. Ko tọjọ ko tosu agbado wọnyi nhu o si bẹrẹ si iyọmọ. Ninu rẹ on paapa alara njẹ, ẹiyẹ abami yi paapa si njọ pẹlu.

Bi igba ti nlọ lori awọn agbado wọnyi ni o bẹrẹ si gbẹ, ẹiyẹ abami yi ba da Adẹtẹ yi ni imọran pe bi awọn ti ṣe nfẹ ọ p ọ l ọ p ọ awọn ohun elo to, ti awọn ko si ni, a dara ki a w ọ n kore agbado ti o ti ngbẹ yi ki awọn si ta wọn, ki awọn fi le ni anito ati anişẹku nkan.

Bi nwọn ti kore yi tan ni Adẹtẹ yi ba d'ẹru, ni o ba gbe lọ si ẹnu ibode ilu kan ni agbegbe igbo ainireti aginju na, ko tile mọ pe ẹnu Ibode inu ilu ti on ti jade ni on tun gbe ọja pada wa fun tita, gẹgẹ bi alebu enia ti nwọn ti sọnu s i n u igbo ainireti yi. A se iyan ti nmu ni olu ilu yi lati ọjọ ti wọn ti le ọdọmọkunrin adẹtẹ yi kuro ninu ilu, ti o si ti fi awọn ẹbi rẹ ti o ni ati awọn ọmọ ti o bi ati awọn ile nlanla ti o kọ silẹ.

Gbogbo enia inu ilu na fẹrẹ ku tan, eyi mu ki awọn igbimọ ọ b a ilu yi dorikodo lori ọrọ iyan ti o nmu na. Ọrọ wa di ọrọ owe ti nwọn npa wipe "Agbagba ki wa lọja ki ori ọmọ titun ki o wọ". Ọba gba imọran pẹlu awọn ijoye rẹ. Ninu awọn ibere rẹ eyi ti o jẹ k o k o nipe "Ọna wo ni awọn yio gba ti onjẹ yio fi gba wọ ilu, ti awọn yio si tun ma ta fun awọn ara ilu.

Owo si wa nilu yi pupọ asẹhinwa, asẹhinbo ẹsi ti a w ọ n Igbimọ fi da ọba yi lohun gẹgẹbi ibere rẹ fun iranlọwọ ilu ni pe ẹnikẹni ti o ba ti le mu onjẹ wọ inu ilu na wa, on ni ọba yio mu ni igbakeji rẹ ati lori oluwarẹ na ni nwọn yio ti bẹrẹ si jẹ ọba titi de irandiran rẹ.

Ohun gbogbo ti isi ṣe alumọni ọba titi de ori awọn iyawo ti o ni meji meji ni on a t i oluwarẹ yio jọ pin.

Nwọn lu agogo ileri yi si ita fun gbogbo awọn ara ilu kakiri lati gbọ ati lati bẹrẹ iṣẹ ni ṣiṣe lori rẹ.

Bi o ti di owuro ti akukọ nkọ ni fẹrẹtẹ, ni adiẹ yi ti bẹrẹ si bọwa si ẹnu bode ilu na lati wa ta oja rẹ. Bi o si ti de ẹnu'bode lati wa ta ọja na, o ba arakunrin kan lẹnu ibode o si bi lere wipe njẹ ilẹ ti mọ bayi ?

Ọkunrin ti adẹtẹ yi ba pade lojọ na si ba dunadura iye ti yio ta aperẹ agbado rẹ, adẹ'ẹ yi n i Ọkẹ mẹrin ni, ọkunrin na sanwo lẹsẹkẹsẹ.

O ni ki adẹtẹ yi si duro de on na on mbọ wa, o w a gbe lọ taperẹtaperẹ lọ s'ọdọ ọba. Inu ọba si dun gidigidi ọba na ni ki n w ọ n lọ ranṣẹ pe awọn Onilu on pẹlu awọn Onifere wa. O n i k i nwọn mura fun ẹsin ki nwọn si mu aṣọ ti wọn o fi gbe adẹtẹ sori ẹsin na wa.

Nigbati nwọn nlọ omokunrin yi lo gun e s i n yi lo, sugbon nigbati nwọn de ibi ti adẹtẹ yi wa nṣe ni nwọn mu aṣọ ẹtu ti wọn mu dani yi ni wọn fi wọ ọ lewu nwọn gbe sori Ẹsin na. Enu si nya adete yi titi wọn fi gbe de agbala Ọba.

Ọba si ṣe gegebi ileri r ẹ lesẹkẹsẹ Kotọjọ-kotosu iyawo ti ọba fi d- adẹte yi lọla si loyun o si bi ọdọmọkunrin kan o s i n y a gbogbo awọn ara ilu lẹnu pe Adete yi tun le bi mọ.

Nigbati adẹta na fẹ s'omo yi loruko o s ọ n i "Oluwa Sunmibare".

Ki ọba ilu yi to W'aja, ọmọkunrin adẹte yi ti to ọba jẹ, gbara ti ọba si w'aja tan ni ọmọ adẹtẹ na ba gun ori oye.

Lati ọjọ yi ni ọba jijẹ ti kan iran awọn adẹtẹ yi. O si pada si ipo rẹ atijọ. Ki Oluwa Ọba Alanu julọ sun ori onikaluku wa ba rere o.

## Woli Kan Fi Owo Ra Ewon

IFỌ—Ni ọsẹ ti o kọja ni Adajọ Kotu ibilẹ ni ki "Woli" ijọ Ṣọṣi awọn Serafu ọkunrin kan ti orukọ rẹ njẹ Michael Adewusi fi ọgata ponun tanran tabi ki o lọ s'ẹwọn oṣu Mẹfa fun ẹsun ti awọn ọlọpa fi sun wipe o fẹ fi ọmọ-ọlọmọ ṣe aya.

Nigbati nwọn bẹrẹ si ro ẹjọ na, awọn ọlọpa ni, nigbati 'Woli" yi ri ọmọge na, oju rẹ ko kuro lara rẹ rara, o si sọ fun ọkan ninu awọn obinrin ẹrirán ti o wa ninu Ijọ rẹ ki o parọ wipe on riran si ọmọge na pe ti ko ba fẹ Woli yi ki o fi ṣe ọkọ, ọkọ kọkọ ti o fẹ ibẹ ko ni san rara.

Nigbati ọmọge na gbọ eyi, inu rẹ, bajẹ ni woli yi ba mu u lọ si Ibadan lati fi se aya laisọ fun awọn obi ọmọdebinrin na.


## OKUJA WO'LU

NIGBATI ỌJA KO BA TA, TI ẸNITI O RA ỌJA KO TA EYITI O RA. BAWO NI YIO ṢE LE RA OMIRAN, EYI NI OGUN TI ONIṢOWO LE ṢE TI ỌJA LE FI MA TA

BI IṢU AKARA GBIGBONA.

POLOWO ỌJA RẸ SINU ELETI—ỌFẸ

E Ma Ka Iwe Irohin Eleti-Ofe

ELETI-OFE D'ARABA

# ELETI--OFE

ANJUWỌN KO ṢE WI L'ẸJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM
28, Kosọkọ Street. Lagos. "ELETI ỌFẸ," LAGOS

P. O. Box 467 Phone 23370.

VOL XIV. No. 827. SATURDAY JULY 7,- JULY 13, 1962.


# Agbo, Ako Gba

Inu wa dun lati ri Dokita Adekoye Majẹkodunmi, alamojuto Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun nigbati o ko gbogbo awọn Ijoye ati Ọba, awọn tiṣe ọmọ ẹgbẹ ile Igbimọ awọn Oloye Ipinlẹ na jọ, ti o si ba wọn sọrọ gẹgẹ bi ọmọ ti mba baba rẹ sọrọ, ti o si ṣe alaye lori ọpọlọpọ nkan ti o ṣẹlẹ si Ijọba Ipinlẹ na fun wọn yepeyepe.

Ṣugbọn nkankan ni o ba ehin aja jẹ, iyẹn si ni imọran nla kan ti Dokita Majẹkodunmi mu ẹnu kan. Imọran na nipe, on bẹ wọn ki nwọn jọwọ, ti nwọn ko ba fẹ wahala ati idamu ni agbegbe ibiti nwọn gbe j'ọba tabi jẹ oloye si, ki nwọn ye faramọ ẹgbẹ oṣelu kankan. Ko ba ṣe ẹgbẹ Alaake (NPC) ni tabi ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) ni tabi ẹgbẹ Afẹnifẹre (AG) ni. O ni baba ni awọn ijoye yi jẹ fun gbogbo wọn.

Imọran yi dara pupọ, sugbọn awa oniwe irohin Eleti-Ọfẹ gẹgẹbi agbọrandun gbogbo awọn ara ilu, ati pe ti Dokita Majẹkodun ba si fẹ ki a sọ esi ti gbogbo awọn ara ilu fi s'ọrọ rẹ na si on leti, iyẹn ni A gbọ, sugbọn A KO GBA.

Otitọ ọrọ bi isọkusọ ni o nri. Bi Dokita Majẹkodunmi paapa alara ba tilẹ fi ojọ miran wo imọran yi, a ri wipe ko ba oju mu rara. On paapa gẹgẹbi ọmọ Ẹgba ati Oloye kan ni Abẹokuta ko gbọdọ sọ wipe kinni ti awọn Parakoyi jẹ ninu awọn oṣelu tabi awọn Balogun ati awọn Apena adugbo kọkan. Ki awọn Oyinbo to de ilẹ yi ni awọn Ọba wa ati Oloye wa ti nfaramọ saraki saraki ilu ti o ba wa nigba, ti nwọn si di opo Ijọba ilu mu ni akoko na.

Ki a wa da silẹ, ki a tun koo, bi ọrẹ wa Dokita Majẹkodunmi ba gba awọn ọba ati ijoye Ipinlẹ Ariwa l'oke ọya ni imọran agbara bayi, ko ni gba iyi ati ẹyẹ lọdọ wọn titi ti yio fi kuro nibẹ.

Ṣe Alhaji Amọdu Bello, Sardauna ilu Sokoto ni ko sọ wipe on ko ni faramọ ẹgbẹ Alaake (NPC) ni tabi Ọba Kano ( Alhaji Mọhamọdu Sanusi ) tabi Sulu Gambari, Ọba Ilọrin. Gbogbo awọn ọba ati ijoye ti a darukọ wọnyi ni nwọn lọwọ ti nwọn si lẹṣẹ ninu ẹgbẹ oṣelu, ti nwọn si di opo Ijọba mu ni ilu wọn.

Adekoye, a gbọ, sugbọn a ko gba !

# Iwe Si Olotu

## Ijoba Onigbese Ko Dara

A gbọ wipe awọn Ijọba Apapọṣe ilẹ Nigeria ti tun nmura lati tun lọ ya owo gọbọyi kan lọwọ awọn Ijọba Oyinbo ajoji kan ni Okẹ-okun, ati pe ti nwọn ba ya owo na tan, nwọn yio pin fun awọn Ipinlẹ Ijọba ti nwọn ni nkan l'owo ṣe; awọn bi ipinlẹ Ila Orun ni ilu awọ Ibo ati Ipinlẹ Ariwa ni ilu awọn Hausa pẹlu Ijọba Apapọṣe l'Eko

A tun gbọ wipe kinakinni ti o ba ku nilẹ ninu owo na ni nwọn yio fun Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun, nitoripe nwọn ro wipe awọn Yoruba ti o wa ni Ipinlẹ na ko pọ rara atipe Ijọba wọn ni owo Koko (cocoa) lọw ti nwọn le lo fun awọn ara Ipinlẹ na.

Nwọn tun fi ye wa wipe Ijọba ki Ijọba ti o ba nlọ kakiri ti o nya owo, abuku ni nwọn nma fi kan awọn enia orilẹ ede na ni ilu okere atipe nwọn si nma bu ẹtẹ lu owo ilu na nibiti nwọn ba gbe tẹ fada-aje (money market) owo ilẹ na ko si ni ni iye lori pupọ l ti le fi ra nkan parọ ọja ti wọn.

Bi iru alamọri bayi ba wa ninu ọrọ Ijọba wa ti nwọn nsaṣihin, safe sọhun lati ra gbese mọ wa lorun, o yẹ ki ṣe ikilọ fun wọn ki nwọn lọ joko jẹjẹ ki a tẹpa mọ iṣẹ lati ṣe nitoripe iṣẹ-ṣiṣe ni oogun iṣẹ.

Emi ni,
S. Aralamọ
Abẹokuta.

## Ekiti Nfe Titi Oloda

Nwọn ni bi a ba nsọkun a mọ riran iyẹn ni ti awa ara Ekiti ni Ipinlẹ Iwọ Orun. Olotu, inu wa yio dun bi ẹ ba le ba wa fi ẹdun ọkan wa yi s'i etigbọ Dokita Majẹkodunmi alamojuto Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ki nwọn ba wa da ọda si oju titi wa lati Iye si Aiyetoro nitoripe oju ọna na nti wa loju.

Bi a ba ṣeni lore ọpẹ laa du a si dupẹ pupọ lọwọ awọn ẹgbẹ Afẹnifẹre (AG) nitoripe nigbati Ijọba na wa lọwọ wọn, nwọn ba "le tiro fun oju ọna-titi Ọtu titi ti o fi de Ishan.

Ofid pajawiri ko ṣe ofin-pajawiri, ẹ jọwọ ẹ ba wa tun ilu wa ṣe.

Emi ni
O. Ọlaoye
Iye-Ekiti

## Awon Minisita Onigba Ojule

Nwọn ni orin ni, ṣaju ọtẹ: laipẹ yi niwọn nkan bi oṣu kẹta ni a nka irohin kan lati inu iwe Ayiluka pe awọn Minisita kan ninu awọn ti a fi ijanu Ijọba le lọwọ nkọ ile mọle nwọn si nkọ pẹtẹsi. Ayiluka na si fun wọn ni orukọ kan eyini ni Minisita Onigba ojule.

Kakiri ilu Ibadan lọjọ oni, ibikibi ti o ba de wa ma gbọ tọmọde tagba ti nwọn nkigbe awọn Minisita Onilegogoro lọtun losi.

Mo gbọ wipe nwọn ti bẹrẹsi fi awọn Minisita Ọlọkanju aṣe ẹlẹya nilu awọn Aganyin ni Ghana.

Olotu tani a ri bawi ? ṣe awa na ni a ko le kaju ọkanjuwa wa. Nwọn fi ọ jọba o tun nwẹ awure; kinni o fẹ da ? Boya o fẹ di Ọlọrun ni.

Awọn Babalawo ti yọ ODU ti o ba ọrọ awọn baba minisita Ọlọkanjua na lọ ninu ọkan ninu ẹsẹ wura wọn, nwọn ni Ọrunmila ni eke a ma pa eleke ọdalẹ a si ma pa ọdalẹ on ni Ifa ti a da fun amokun-ṣole ti o ni ọba aiye ko ri on; bi ọba aiye ko ri i ṣe ọba ọrun nwo. Abọru bọye !

O di ọwọ nyin, ẹnyin enia wa.

Emi ni,
Ọmọ Abati

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

(LATI OWỌ AYILUKA)

IBADAN L'O MỌ

Emi Ayiluka tun de o; Ibadan ni ẹnyin mọ, ẹ ko mọ Layipo. Tele-tele mo ti sọ wipe ki nto lọ si Ibadan tabi ibiti o ba jinna diẹ to ibusọ mẹwa nitoripe awo'rawọ mi ṣe ikilọ kan fun mi wipe ki nmọ lọ si idalẹ ti o jinna pupọ. Ṣugbọn iwe kan ti mo ri gba lati owọ alagba kan, Ọgbẹni Ọlọgọjọ, ni o jẹ ki nda kaan lọ si Ibadan ni ile Oluyọle.

Eleyi ni iwe ipe-ṣ'ẹyẹ (invitation card) na ti mo ri gba lati ọdọ Ọgbẹni na, BỌ SI KỌNA KI O KAA WO:

"Ẹ jọwọ alagba, boya ti ẹ ba ri iwe yi ẹ ko ni sọ wipe mo nṣe iyaju si nyin, ṣugbọn nkan ti mo fẹ sọ na ko pọ pupọju.

"Ẹ jọwọ, inu wa yio dun bi ẹ ba le jẹ ki Ọgbẹni Ayiluka Eleti-ọfẹ wa si ibi ipade wa ti Olori wa Oloye A. Akinloye pe ti a fẹ ṣe ni Oje ni Ibadan. Ipade na a dun pupọ boya Ayiluka paapa le ni ọrọ ti yio fi gba wa ni iyanju nibẹ, nitoripe nṣe ni a npe gbọn, a ki pe gọ.

"Ti o ba fẹ wa, ki o tete wa ni owurọ ni nwọn nkan bi agogo mẹjọ abọ, ki o bere mi lọdọ awọn agbero mọto ni Bẹrẹ, ṣugbọn ni irọlẹ patapata ni mo ro wipe a o ṣe ipade wa na ni ita Oje.

Emi ni,

B. Ọlọgọjọ."

O yẹ ki ẹ ba mi dupẹ lọwọ alagba wa, Ọgbẹni Ọlọgọjọ. Ibadan ti mo lọ na na ṣe mi ni ire pupọju. Mo di ỌMỌ DẸJU KO RI'MU. Eti mi gbọ ọpọlọpọ ọrọ, bẹsini oju mi ri oriṣiriṣi nkan. Gbara ti mo kọ de ilu Ibadan isọ iya Mulika "Aday'odun" ti ilu Ibadan ni mo kọ gba lọ, nitoripe mo fẹ wọ "sokoto" ife ẹmu meji lọdọ rẹ ni Gbagi.

O MỌ LAYIPO

Ọpọlọpọ awọn ojulumọ enia lọkunrin ati lobinrin ni mo ba pade ninu isọ "Aday'odun" na. Ṣe emi Ayiluka paapa tiṣe sanmọri pupọ ni ilu Ibadan ri. Mo ba awọn diẹ ninu ọmọ ẹgbẹ KILỌKỌ—O—SE ati "AWA—LA—NI Ibadan" pade nibẹ. Owo atijọ ti mo ko s'apo bi ara oko fẹrẹ ko abuku ba mi, lọpelọpẹ mo ti mọ Ibadan lọjọ ti o ti pẹ. Nwọn ṣe mi ni alejo, emi na si ṣe alejo diẹ fun awọn ti nwọn le sin mi de ibiti ẹru ko ni ba mi.

Inu Ọgbẹni wa, Ọlọgọjọ paapa dun lati ri mi ninu tasi (taxi) ti mo ti gb'ẹru kara-kara ki nto de ọdọ rẹ. Wara were ti a ti de Bẹrẹ a ti bọ sinu mọto miran, a lọ si ile Oloye Akinloye nibiti nwọn ti nṣe ipade.

Irohin abọ ipade wa na ma mọ jẹ ki gbogbo ẹnyin ọkawe mi gbọ lọsẹ ti mbọ; ṣugbọn mo fẹ ki ẹ ba mi dupẹ lọwọ Ọlọgọjọ-ko-jẹun-igbiwo.

KILO BA Ẹ DE'BẸ ?

Ibadan lo ni ayo-tita lọwọ ni lọlọyi. Bi o yi sihin, Ibadan, bi o tun yi sọhun, Ibadan. Mo yi ẹrọ redio mi si ilu Oyinbo laipẹ yi, irohin ilu Ibadan yi ni mo gbọ ti ẹnikan ninu awọn onirohin ibẹ fẹnukan.

Mo gbọ wipe ọrẹ mi Oloye Festus Ọlawọyin Awosika, alaga ibiṣẹ Western Nigeria Marketing Board kuro ninu ẹgbẹ Afẹnifẹre ati pe ki o to kuro nibẹ o fi ohun s'lẹ ninu iwe ti o kọ si olori ẹgbẹ na, iyen Oloye Obafẹmi Awolọwọ.

Kilode, FOA? Ki a mọ ṣe ọrọ na ni ọrọ bi Oyinbo ba fẹ lọ ti nwọn ma nya igbẹ sori aga.

Ki a niran gbogbo ọjọ igbati a njọ nṣee ni FAA-KAJO-JA. Ki a niran igbadun afefẹ ti a gba lori ẹgbẹ Afẹnifẹre yi nilu Oyinbo; ki a mọ se gbagbe igbati gbogbo aiye nri orukọ wa ninu owo Korẹnsi gẹgẹbi aṣoju ẹgbẹ Afẹnifẹre yi. Ija lo de orin d'owe.

EYI JẸ......

Mo niran igbati temi FOA jọ ngbe igba-aworan (camera) kiri l'Eko niwọn nkan bi ọdun mẹdọgbọn sehin; ọrẹ mi Oloye Awosika nṣe iṣe tisa-onifoto, emi nkọ iwe fun awọn oniwe irohin kan l'Eko, mo si tun nya foto mi larin awọn gbajumọ oṣelu igbani, emi pelu Ọgbẹni Milton Macaulay (on na fẹ di oloye na, boya ni adugbo Ojunto ni Massey St nitori nanu rẹ Ologbe, Dorcas, ṣe kudu-kudu meje sibẹ nigbati o wa laiye) pẹlu Ọgbẹni wa Disu, baba oni-buredi ni Macarthy Street l'Eko.

Fẹstus Ọlowọyin, ko ye mi rara nkan ti o ba ẹ de ibi EYI jẹ, EYI-KO-JẸ. Ọrọ a mba wọn se ilu ọrẹ EYI JẸ, EYI-KO-JẸ ni. Ọpọlọpọ enia ni nwọn ti ibẹ di gbajumọ ti nwọn si di olowo ati onile; ọpọlọpọ lo si ti di ẹni abuku. Sugbọn ti ẹ ye ẹ o, ọrẹ mi FO nitoripe "TỌBỌ YE ỌBỌ". Temi paapa ti mo mbẹrẹ mọlẹ, ti mo umu namba ye mi.

EYI KO JẸ...

Mo gbọ wipe o fẹ lọ si idale lati lọ bẹ awọn oniṣẹ ti o wa ni itọju rẹ wo, jọwọ ti o ba de ọdọ ọrẹ mi, Baba Ogbomọshọ, SLA., baba Ọmọdele ni mo wi o, ki o jọwọ ki o ba mi ki Oloye Akintola na daradara. Ki o ba mi sọ fun un wipe lati igbati o ti de Olokemeji ko tile gbiyanju lati san owo-ilẹ fun mi, tabi ko mọ wipe oko baba mi ni Olokemeji titi ti o fi de Abule Atakan.

Ki o maṣe gbagbe lati fi apa-ọya ranṣẹ si mi pẹlu itan ẹtu ati eran igala. Emi paapa alara ko le wo'ko ẹran igbẹ mọ.

---

**Plushes, Velvet, Velveteens Damask**

**& Building Materials**

PLEASE CONSULT

**Okunowo Brothers**

( 63, Massey Street, Faji Market )

LAGOS NIGERIA

The House Where Courtesy & Satisfaction are Guaranted.

# Eru aiye ma mba mi (3)

( Lati owo J. Ola. Wins )

## ẸNU ARAIYE L'EBỌ

OKAN eni ni igbagbọ eni, ọrọ mimọ Ọlọrun sọ fun wa wipe ki o ri fun wa gẹgẹbi igbagbọ wa. Ṣugbọn aiye yi ti yatọ patapata. Bi enia ba dawọ le nkankan ti oluwarẹ ba gọ die ti nkan na ba yọri si rere aiye a so wipe ko le se ki o m ọ ri bẹ, o ti fi ara balẹ pupọ ju. Bi nkan na ko ba si yọri si rere aiye kan na atun sọ wipe hẹ! iwọnba ni enia gọ mọ. Bi ẹniti o ba gbọn ba d a w o le nkankan ti nkan na ba yọri si rere: a ye a so wipe k o le se ki o mọ ri bẹ, ẹ ri wipe o ti be ju bo ti yẹ ki nkan rẹ ri ni yẹn. Bi ko b a si yọri si rere, aiye yi kanna ni yi ma wipe, hawu! tirẹ ti p ọ ju, o tilẹ bẹ ju toro ti o kọ de lọ, ara enia ba yẹn ni nkan rẹ yọri si rere ti ẹ gbọ ?

Bi enia ba ga, aiye a sọ wipe o g e f o ire bi o ba si kuru aiye kanna ni yio tun sọ wipe ko ga to ire. Ẹru aiye m a w a nba m i g a n ni. Olorin kan lo n k ọ o r i n bayi, "ọna wo ni ao gbe gba ti a l e fi k o aiye ja, bi o bo bọ siwaju nwọn a ni o tẹ 'ku lori, bi o ba si bọ si ẹhin awon a tun ni o tẹ arun mọlẹ; bi o ba si wa bọ si arin, nwọn a tun ni o se afojudi, ọna w o ni a gbe g b a ti a le fi ko aiye ja".

Aiye ni o wipe aiye gun aiye na ni o s i tun wipe aiye ko mọ gun mọ, aiye ni o nsọ ọmọ di ale. Melo ni ki asọ melo ni ki a ro ninu nkan t i aiye n s e. Ninu Bibeli Mimọ aiye lọ wipe Hosanah ! Olubukun ni ẹniti nbọ wa ni orukọ Oluwa, gbogbo enia n t ẹ asọ rẹ silẹ ẹniti ko ri asọ tẹ, nja imọ-ọpẹ nwọn n f i yẹ Oluwa wa Jesu Krist si. Awọn aiye kan n a n t o wipe kanna m ọ agbelebu, ẹda kan na ni ẹ kan Jesu mọ igi oju aiye lẹri yẹn o ẹ kan.

Melo ni ki a ka ninu awọn enia ti ẹnu ar'aye ti baje, ọpọlọpọ ti di ero ọrun alakeji ti ẹnu ti pa. Ẹnu ar'aye ni ebọ. Nitoripe ko si orisa kan nibi kan-kan. Orin kan lọ bayi:-

Ọmọkekere ẹnu l'ẹbọ o,
Ẹnu lebọ;
Agbalagba enu lẹbọ o
Ẹnu lẹbọ;

K'enu mọ pa mi mi sọnu l'ewe ẹnu, l ẹ b ọ, gẹgẹbi mo ti wi, ẹnu ni ẹbọ.

Itan kekere kan lọ bayi, ni aiye atijọ ti awọn enia nma gbe oko tabi aginju igbẹ, nigbana bi oku ba ti ku, nwọn yio sin sinu erupẹ. Sugbọ nigbana pipa ni nwọn mọ pa ole, nigbana nwọn a pa omiran sinu igbo, nwọn a pa omiran sinu ọdan.

### Aro'ko

Ninu ole ti nwọn pa yi, ọkan wa ninu papa oko kan, ti ọkunrin kan si ma ngba ibẹ lọ si inu oko re. Ṣe awa na si mọ wipe lojojumọ; ni arọ ati ni alẹ; nwọn a si mọ pe ni oko arọ ati oko alẹ.

Bi o ti di ọjọ kan ti ọgbẹni na nlọ si oko arọ, ni o ba ta'ju kan ti o ri ri ori enia ti o ti gbẹ ti o da joko ninu papa. Kaka ki ọkunrin yi ma ba ọna oko rẹ lọ, ki o si moju to ọna onjẹ ojọ rẹ; awọn Yoruba "ni boju ri ẹnu adakẹ" tabi "ẹnu-mọmọ-ẹnu- ete-momọ-ete ni ko ẹran ba ẹrẹkẹ". Ẹnyin na ẹ fi oju inu woo, ki enia sọrọ-kọrọ ni afin ọba ni aiye atijọ, aburadi ni ọwọ yio pade ni ẹrẹkẹ ati eti oluwarẹ.

Ọkunrin yi wo ori gbigbẹ ti o joko na titi, o ni "ori gbigbẹ, o ma ku ijoko o iyẹn da lohun wipe 'ẹnu rẹ ni yio pa ọ."

Nigbati o nti oko arọ bọ, o tun w i bakanna, iyẹn tun da lohun bakanna, wipe ẹnu rẹ ni yio paa; sugbọn ọgbẹni yi ko ka eyi si nkan pataki. O wa ti mọ lara lati mọ ki ori gbigbẹ yi lojojumọ.

### Enmo

Nigbati o wọ lara, ni o ba kuku tọ ọba ilu na lọ, o ni on mọ ri nkankan to, Iwọ ọba eti rẹ melo? Ọba ati awọn ẹmẹwa rẹ ni kin-ni o ri gaan. Ọgbẹni na ni, ni ọna oko on, ori gbigbẹ kan wa nibẹ ti o mo nsọrọ, gbogbo awọn ni ,ha! ha!! o tun gbe irọ de."

O ni ki ma se irọ ni o. Oba ni ti awọn ba de ibẹ ti ori na ko ba sọrọ, on yio ti oju rẹ yọ ida, on yio ti ẹhin rẹ fi bọ akọ, (itumọ rẹ ni wipe on yio bẹ ori rẹ danu lọrun rẹ). O ni ko buru, o ya nwọn si tẹle e.

Ọba ba di gari fun ẹṣin rẹ, gbogbo awọn ẹmẹwa ọba gba tii Ọgbẹni yi paa-pa ni o ṣ i w a j u ọba ati awọn ẹmẹwa rẹ tẹle titi ti nwọn fi de ibiti ori gbigbẹ na wa, ọba ni ọgbẹni wa pe bi o ti pe o, were o ti bọ si ibi ti iti ma duro ki ori gbigbẹ na.

### Ori

O ni o r i gbigbẹ, o ma ku ijoko o iyẹn ko dahun rara, o wi-wi-wi, ori gbigbẹ ko ma da lohun o.

Ọba sọ fun wipe ṣe o tan ni'dirẹ tabi k'o tan ni'dire? Ọgbẹnt yi wa n w o l ẹ bi ẹniti o nda'fa. Ọba ni o ya, ẹ bẹ ori rẹ, bi ọkan n i n u ẹmẹwa ọba ti ju ida si lọ-run, ti o ori rẹ nfo lọ ni ori gbigbẹ na wa dahun wipe ṣe "on sọ wipe ẹnu rẹ ni yio pa ọ"? Ẹpa ko ba oro mọ. Ọgbẹni yi ti ku, ori gbigbẹ si ti sọrọ.

(Iyoku di ọsẹ to mbọ)



**Awon obinrin yi nlo si oko won ninu ojo ni owuro kutu-kutu.**

# No "walk in free ticket" to Britain

## New U.K. Immigration Act Now In Force

(By Our London Correspondent)

London -- Last week Saturday was an immigrant week-end throughout Great Britain. On that day the station platforms, harbour wharfs and aiport lounges were filled up with a large number of incoming immigrants who made all efforts to beat the midnight deadline before the new U.K. Commonwealth Immigration Act become law at midnight.

I was at the Airport watching chartered aircrafts bringing in West Indian immigrants, many with their wives, children, mothers and their grandmothers.

The heaviest number of immigrants ever handled was on last Saturday morning. Thousands of Commonwealth immigrants from different parts of the world poured intoBritain like swamps from Cyprus, Pakistan and Jamaica.

### Too Late

One Lucien Pickett, an aircraft pilot from West Indies was under special orders to carry his passengers – totalled about one-hundred, to England before the Act came into law.

His plane, bound for south of London airport, was 56 minutes behind the time limit for "walk in free ticket to Britain."

### Nigerians

Over two hundred Nigerian students hurriedly landed in Britain before the dateline last week. Many of them were Government sponsored scholars while some were private students from different parts of the country.

An official at the London Airport told me that there was nothing to worry about, about these Nigerian students. The Home Office has stressed the point that the aim of the new Act was not to discriminate, but to stop people coming in large numbers.

All immigrants now coming to Britain to work must carry Ministry of Labour vouchers and may be barred on health ground or for their Criminal past.

# InGermany Now



**Former Boxing World Champion, Hogan Bassey, now touring Germany is here seen in this picture practising boxing with a partner. Bassey who was in Germany on the invitation of Mr. Hermann Krause, President of German Boxing Association will be away for two weeks.**

**The best bilingual weekly is the Eleti–Ofe**

**Always advertise in it and read it.**

# IROHIN SOKI

(Lati ọwọ Ayiluka)

## Iwe Aru

Lati iwọn iwọn bi ọgọrun ọdun ti a ti n ba nwọn lo ni ilu Oyinbo (eyiti awa Yoruba nma pe ni ilu Ọba ni aiye etijọ), ti awọn ọmọ wa si nma lọ si ibẹ ti nwọn si ma jẹ aiye falala, an i se mi leti sọ fun gbogbo ẹnyin ọkawe mi wipe ni oru ọjọ ọsẹ ijẹje ni awọn Ijọba Gẹsi fi ikele le oju ọna a ti wọlu, nwọn si ti ilẹku ilu wọn na gbọingbọin.

Ninu ofin-titun ti o ṣẹṣẹ jade na ti nwọn npe orukọ rẹ ni Immigration Act ti o ba fẹ lọ si ilu Oyinbo, o ni lati jẹ ẹniti arun kan tabi amodi kan ko si lara rẹ rara, iwe rẹ si ni lati mọ korokoro lọdọ awọn ọlọpa; iyen nipe nwọn ko ba ẹ ṣe ẹjọ arufin kan ri ninu rẹ ki o to jade; bi o ba si jẹ "Alabi-wọṣẹ" ni o fẹ ṣe nibẹ, o ni lati gba iwe-aru (labour Voucher) rẹ lọwọ ki o to wọkọ nibi.

### Ilu Oyinbo

O yẹ ki a tilẹ kan saara si awọn Oyinbo Gẹsi yi nitoripe awọn ọmọ wọn paapa ti fada kọri. Nwọn ni awọn AJẸREKE ko jẹ ki awọn ri iṣẹ ṣe mọ, gbogbo iṣẹ gbaa ni nwọn gba lọwọ awọn tan.

Iwọ na tilẹ wo o, bi awọn AJẸREKE yi ba mbọ wa si ilu Oyinbo, tile-tile ni nwọn nwa, ọmọ, iya, ọmọ-ọmọ, iya-iya pẹlu baba ati baba-baba, awọn enia bi igbaa a si gunlẹ lẹkansoṣo. Họwu'! a ki bani tan ki a fani ni itan ya.

### Oja E...

Awọn ọlọp'aa kan ba wọn na ọja ẹru tita ninu ile kan ni Ita Balẹ Olugbode ni Ibadan ni ijẹrin. Nwọn ba awọn ti o nta awọn ọmọde lẹru na duna-dura, nwọn si san ẹgbeta pọnun (£600) lori ọmọdekunrin kan ti o njẹ Rafiu Iyanda, ọmọ ọdun mejila.

Awọn iya ati baba ti nta awọn ẹru na tun mu awọn ọlọpa'nu yi lọ sinu agbo ile kan nibiti nwọn sọ wipe awọn fi awọn meji ti awọn tun ni lati ta pamọsi. Nibiti nwọn gbe ti npelemọ lati mu awọn ọmọ meji na jade fun tita ni olobo ta wọn, ni wọn ba salọ, ṣugbọn ọwọ ọlọpa tẹ ẹnikan ninu wọn.

### Ile Mehaya

Gẹgẹbi iwe kan ti mo ji ka lọdọ awọn oṣelu ẹlẹgbẹ Alakuko (NCNC) ti nwọn di opo munisifa ilu Eko mu, mo ri wipe la pẹ yi ni nwọn yio ṣe iwe idinwoku ile mehaya ti nwọn ti bu owo si lori gọbọyi ni ilu Eko.

Mo gbọ wipe awọn minisita ati awọn alagbara ti o kọ ile onigba-ọjule ni ko ti jẹ ki nwọn ti gbe iwe ọrọ idin owo ile yi jade nitori gbogbo wọn ni nwọn fẹ la ọla ọjọ.

Mo ji ọrọ yi sọ fun yin ni.

### Ori Enia

Olofofo kan ti mo fi si Ẹnugun ni Ipinlẹ Ila Orun sọ fun mi wipe ni ilu Ikom ori ọmọ enia wa jaburata fun LILO nibẹ. Ori Ibo ọkẹ marun, ori Hausa ogun ọkẹ, ori Yoruba igba ọkẹ pọnun ni awọn nta wọn.

Awọn ọlọpa lati Kalaba (Calabar) ti bẹrẹsi ri si ọrọ awọn ti nwọn nta ori-enia na ninu ile oriṣa Abaragba lagbegbe Ikom. Ori okuenia merindelogbọ ni nwọn ri ko ninu ile kan.

### Aiye Di Loya

Ninu iwe waya ti a ri gba lati ilu Oyinbo lọsẹ yi, awọn ọtalerugba-o-le-mẹrin (264) enia-dudu ti nwọn nkọ iṣẹ loya ni a gbọ wipe nwọn ti yege ninu ẹkọ wọn, nwọn si ti sọ nwọn di loya, ọkan ninu wọn ni akọbi Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, olori ẹgbẹ Afẹnifẹre ti o njẹ Oluṣẹgun. On na si di lọya bi baba rẹ nisisiyi.

A ki Oloye Awolọwọ na ku orire.


# Lagos Race Club

**There will be racing**

**TODAY**

FIRST RACE AT 3 P. M.

**Come One Come All.**

Secretary
Lagos Race Club.



## NIGERIAN PORTS AUTHORITY

INVITATION TO TENDER

Tenders are invited by the Nigerian Ports Authority for the purchase of such Scrap materials as the Authority may offer for disposal (with the exception of any items which may be separately offered for sale during the period 1st July. 1962 to 31st December, 1962, in Apapa Dockyard, Apapa Quays, Customs Quay or any other particular point where the Authority may have scrap metal for disposal in the Lagos or Apapa area.

A copy of the tender form may be obtained from the Secretary to the Authority, 216, Broad Street, Lagos, on payment of a deposit of £5 to the Authority's Cashier, Accounts Department, Apapa Quays. The completed tender form should thereafter be returned to the Secretary in a sealed envelope marked "CONFIDENTIAL-TENDER FOR SCRAP" so as to reach him not later than Friday, 20th July, 1962.

The deposit of £5 will not be refunded in any event to any tender who, upon being advised of the acceptance of his tender, fails to pay for and to remove the materials made available.

Tenderers are warned that scrap available for disposal may comprise both ferreous and non-ferrous materials although it is expected that most of the materials will be ferrous.

During the six-month period indicated, the successful tenderer will be required to remove, at his own expense, whatever scrap is made available for sale (with the exception mentioned above) within 7 days of being notified to do so. He will also be required to make necessary arrangements at his expense for all such scrap to be weighed in the presence of a representative of the Authority before being removed.

The Authority do not bind themselves to accept the highest or any tender.

BAYO KEHINDE.

Secretary to the Autho ity.

N.P.A. Notice No. 729

4th July, 1962.


Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street Lagos Box 467 Phone 23370; OLOTU: OLA. ONATADE, 15, Kosoko St., Lagos.